# Nje iwo ni ojo ti a bi o?



# Nje iwo ni ojo ti a bi o?

Iru ibeere omugo wo ni eyi? Nje enikan wa laye yi ti koni ojo ti a bii!

Gbogbo wa ni a ni ojo kan pato ti a bi wa, ati ibi kan pato ti a bi wa si; beni gbogbo wa ni a n se ayeye ojo ibi na ni odoodun.

Mabinu o; Ohun ti o ye ki n bere ni wipe "Nje iwo ni ojo ibi ti emi? Iyen ni ojo atunbi?" (Ojo ti a bi o leekeji)



Bibi ti won bi o ni akoko je ibi ti ara, sinu idile eniyan, oun ni o so o di omo baba re ninu aye yi. Bakana, bibi re ni eleekeji je ibi ti emi, sinu idile Idile Olorun, oun ni o so o di omo baba wa ti mbe ni Orun

*"Sugbon iye awon ti o gba a, awon li o fi agbara fun lati di omo Olorun, Eyi ni awon na ti o gba oruko re gbo. Awon eni ti a bi, kise nipa eje tabi nipa ti ife ti ara, beni kise nipa ife ti eniyan, bikose nipa ife ti Olorun.* **Johannu 1:12-13**

Bibi ti won bi o ni akoko so o di elese; bibi re ni eleekeji so o di eniyan mimo.

*"Bi awa ba jewo ese wa, Olooto ati olododo ni oun lati dari ese wa ji wa, lati we wa nu kuro ninu aisododo gbogbo".*
**I Johannu 1:9 (NIV)**

Nigbati a ba dari ese re jio, iwo yoo di mimo.

Bibi ti won bio ni akoko se okunfa iku orisi meji fun o: Ikini ni iku ti ara ti o fi opin si igbesi aye eniyan. Eyi si le sele ni igbakigba! Iku yi yoo fi opin si gbogbo anfaani lati beere idariji ati lati gba ododo Olorun. Iru iku keji je ti ipinya patapata pelu Olorun titi layelaye, o si je ona si inu ina ni orun apadi ni ibi ijiya ayeraye. O buru pupo fun "*Okunrin Oloro yen*" debi wipe ikan omi ekansoso le mu iyipada nla de; kii se iru ibi ti o wu o lati wa. O je ibi ti ko ti le si ireti layelaye

# Bibi re ni eleekeji fun o ni anfaani lati bo lowo iku orisi keji

**Ifihan 20:6**
*Olubukun ati mimo ni eniti o ni ipa ninu ajinde ekini na: Lori awon wonyi iku keji ko ni agbara….*

**Ifihan 21:8**
*Sugbon awon ojo ati alaigbagbo, ati eni irira, ati apaniyan, ati agbere, ati oso, ati aborisa ati awon eke gbogbo, ni yoo ni ipa tiwon ninu adagun ti o n fi ina ati imi ojo jo. Eyi ti I se iku keji.*

Didi atunbi je iriri manigbagbe. Eyi ni o pada so emi re po mo Eleda re ti o si so o di omo lekansi. Eyi ko le sele nitori hihu iwa mimo, ipejopo pelu awon eniyan rere tabi lilo si ile ijosin daradara.



# Bawo ni o se le sele?

Nipa gbigba ipo ti iwo wa gege bi eniyan ninu ara; elese kan ti o n duro de iku orisi meji. **Romu 3:23; 3:10**

Nipa fifi tokan-tokan wa si odo Jesu Kristi eniti o se eto lati gba o lowo iku keji, ki o gbadura, ki o jewo awon ese re fun un, ki osi bebe fun idariji. Jowo jewo ese re ni pato fun un.

Lakotan, pe Jesu Kristi sinu okan re ki o si maa gbe ibe titi layelaye. Bi o ba ti gbe awon igbese ti a ko soke yii, gbagbo wipe iwo na ti di ebi Olorun niyen; O ti di molebi awon eni emi, awon ti a ti bi leekeji (awon eni atunbi).

Ojo ibi re ni eyi! Orun kun fun ayo nitori omo tuntun darapo won. Kaabo sinu molebi Olorun!



Jowo ko akosile si alafo ti o wa nisale yii, ki o je akosile nipa ara re; ki o si fi akosile na ranse bi atejise ori ero alatagba.

Logan ni ao kan si o lati fun o ni ounje emi ti yoo ran o lowo lati dagba kun oju osuwon.



Ti o ba ti gba Jesu Kristi gege bi Oluwa ati Olugbala re tabi o n fe alaye sii, Jowo te atejise si:

*ehcnigeria1@gmail.com*

Maa fe lati gba adura fun o ati lati ki o ku orire lori ominira re kuro ninu ahamo (ide) satani.


**Every Home for Christ Nigeria**

7, Adekunle Akala St., Off Fatai Irawo St., Ajao Estate, By International Airport Road, Lagos

+234 (1) 293 2331 | +234 (0) 815 5501 000
+234 - 815 550 2000

info@ehcnigeria.org | www.ehcnigeria.org